The Chief Secretary to the Government
27 JAN. 1925 LAGOS

***Jamat Muslims Appeal Court Victory No.***

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. III. No. 132. SATURDAY, JAN. 24, 1925. FOURPENCE.

***This Week's Circulation 2000.***

## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails, Rangoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

## N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO ***J. F. SICK***

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko

A jẹ Ajirera ninu ǹwò Ilẹkẹ, orişirişi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Olokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumădan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọnyi fun tita:—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aşọ Iş'ọşọ, Ẹrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi ǹwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni:— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# LEVER STORES LTD

## THE PEOPLE'S STORE

NOTHING NEW UNDER THE SUN

BUT ALWAYS

**Something New**

AT

# LEVER STORE

AND

**Nothing over 1s.**

*Editor & Proprietor* —
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

—:o:—

ẸNYIN A J'OMỌ S'APO TI NYIN TI JẸ? B'ÓWO OBÂ BA TẸ NYIN Ẹ O ṢU 'MI DIDUN!

O dabi ẹnipe Waka ti a le gbe nipa awọn jomọ-s'apo-j'ọmọ-s'apo ti nwọn wọ igboro Eko lakoko yi l'eyi; gbogbo ilu lo gbojikan ni Monday ọsẹ yi nigbati a gbọ pe ọwọ tẹ oku ma jẹ lẹ-o-mọ kan ti o gbe odidi ọmọkọnrin kan s'abẹ aṣọ, ti iyẹn si nja pitipiti bi adiẹ to si nmi fukẹfukẹ bi bọnkọlọ; ni ọsẹ diẹ sẹhin ni a sọ sinu Iwe Irohin yi pe odidi ọmọdekọnrin kan pora l' Ebute Mẹta. Ẹnyin Olori ọpa ọba, ẹ jigiri lati fi idan han irufẹ awọn o-gb'ọsan-ta-f'oru wọnyi, nipa kiki wọn wọ lasiko.

"IGI GANGANRAN MA GUN NI LOJU OKERE LA TI NBẸRẸ RẸ."

O yẹ ki awa obi ṣe kilọkilọ tẹtẹ ti awọn ewe wa nta kakiri adugbo nisinsinyi, ti nwọn npe ni ere ṣẹsàn.

A f'oju ri oriṣiriṣi koto ti "awọn abẹbẹlubẹ" wọnyi gbẹ si ibaba ati si ikọkọ fun tita tẹtẹ ṣẹsan na. B'o de'hin, koto! B'o d'ọhun, koto!! Bi aṣa ọrọ Ologbe Alufa ẹni-ọwọ M. L. Stowe, nigbati o sọ ti lu kan t'o de ti o ni o kun fun okuru Igo ọti ofifo, ni aragbabu Ipade kan ti awọn oniṣẹ Ọlọrun (*Missionaries*) ṣe ni'le Afari ogun l'Ẹhingbẹti fun dida owo ọti duro ni'lẹ Yoruba ni ọdun *1895*. o jẹ ẹgbọn ọdun nisinsinyi; a ha le mọ agbalagba melo lo ti ko si irufẹ koto bayi laimọ, nitoripe a ṣakiyesi pe awọn ọmọ wọnyi ki nsaba ndi ile tita tẹtẹ wọn na, lẹhin ti nwọn ba ti ba ẹgbẹ wọn ta tan.

Nijọ wo niyi, ti a kigbe ti *Raffle*, ti ọpọlọpọ t'ewe t'agba wọ lẹkan nibi bi ẹni wọ were.

Ere tẹtẹ ti awọn ewe wa nṣe yi ko ha buru ju ti *Raffle* lọ bi? O tilẹ to ọmọdebinrin miran ti o ngbe ọja ti o nta silẹ, ti o si nba wọn na'wọ gan ere sondoko na.

A fẹ ki ẹnyin ọpa ọba ma le irufẹ awọn ọmọ ti o ba nta ṣẹsan bẹ, ti ẹ ba ri ni opopo-ode; eyiti o ba si nfa tikọ, ki ẹ fẹju mọ pe ẹ o ljẹ ki "Kesita ti mọ'le".

Ẹnyin obi, ẹ si mura lati gba iwa ole yi lọwọ awọn ọmọde wọnyi.

Kekere la ti pe ekan iroko, ti o ba dagba tan' apa ki ka mọ.

ADIẸ SỌKUN IYẸ, IYẸ DI YẸGBẸYẸGBE

Ede to yẹ wa nisinsinyi leyi, niti Ọyọ ti a ti nfẹ ki o sọkalẹ daradara lasiko yi, o gbọ na, Ọyọ na ja ka si nkan lẹnu ọjọ diẹ to kọja, papa ninu ọsẹ yi, tobẹ ti o fi gbe ẹlomiran ni'yawo sile—eyini ni pe ẹlomiran ko ni mọ pe agogo bi mẹjọ ti lu lerọ nigbati o ba ṣi wa lori *Bed* ti o nrọ gidi, ti o si nyi kiri bi igbati ekute ile iba ma yi awusa.

A si rope a ko s'asọdun ti a ba wipe Ọyọ na sọ ọpọlọpọ di aromi mawẹ, bẹ wiwẹ la wẹ k'a to jare Ọyọ.

Ki Ọbangiji maṣai jẹ ki mimu Ọyọ lọdunni jẹ ami alafia, ami owo, ami ọ̀wọ̀, ami ọla, si Eko ati si gbogbo agbaiye—Aṣẹ.

ỌMỌ 'LAKẸSAN, GBE'RA NI'LẸ O DIDE.

A ṣọpẹ gidigidi lati ri pe fifẹ ti o fẹ si Olori, Ọgbẹni T. I. Kester, Kiniun Kotu, ọmọ Alafin Ọyọ lẹhin ọjọ melo yi, ṣe

nfuyẹ bọ, ati pe ko si ni pẹ ki jagun na to tun lọ bẹrẹ iṣẹ.

Piri ni ẹiyẹ olo-ngo n'ji, okunrin ẹiyẹ ki wa lori itẹ. Aṣẹ t' awọn agbalagba!!

## ỌBA ALARAN BẸWẸ KIN-KIN.

[Lati ọwọ AKIRIMANU.]

Si Oniwe-irohin "*Eko Akete*"

Mo ju ba o,

"Awọn agbalagba ma npa lowe pe ninu ofi ola ni ọno pandọrọ ngbo si, nitotọ owo jẹ adeyanju ninu gbogbo ohun ti Ọlọrun Ẹlẹda wa da si ode aiye, ṣugbọn ni ọna keji ẹbun ọgbọn ati oye tayọ rẹ, a ka ninu Bibeli Mimọ pe Sọlomọni fi gbogbo nkan iyebiye ti iba tọrọ lọdọ Ọlọrun sẹhin bikoṣe ọgbọn ati oye ni a gbọ pe o tọrọ lati le ma fi tọ awọn enia rẹ sọna.

Ohun ti o mu wa sọ ọrọ yi ni rogbodiyan ti awọn agba wa ni igboro Eko yi nipa ero wọn lati tun ba nkan jẹ; gẹrẹ ti a gbọ pe Ọgbẹni wa Burrel Vaughan (aiya ni t'ogun lọtọ ọkunrin) tẹ ṣo koto rẹ bọ lati ṣe atunṣe gbọnmi-si-omi oto to wa larin awọn agba wọnyi inu t'ọmọde t'agba lo dun ṣugbọn awọn alaṣeju fi ara wọn han gbangba, lẹhin igbati aṣiwaju wa Ọlọla J. E. Shyngle ni igboro Eko yi ninu igbimọ ti fi ọwọ wọ aiya rẹ ti o si tọ Dokita Randle lo fun atunṣe ọrọ yi ti a si ni ireti pe o to akoko ti ija yio pari ni kini wa mu nwọn lati sọ pe a ko fẹ lagbaja a ko fẹ lakaṣegbe, nitotọ bi Ọlọrun Ọba na ba fi nkan gongo diẹ han awa ẹda bi ẹbun owo ṣe iyẹn lo nmu wa gbagbe pe ẹbun ti a fun ọmọ ko le ba ti baba mu, ṣe Dokita Randle papa mope ẹniti o ba kọ ju biriki oluwarẹ nfẹ ki a ju okuta lu on. Talo ran Belu wọ ọkọ to ni ọkọ da on, bi enia ba ni owo lọwọ werewere ni nwọn ni ko ma fi ṣe tabi nigbati o lọ si ilu Oyinbo lakoko kan fun alafia ara rẹ jẹjẹ, ti o si wa ọna de ọdọ oni'we irohin *West Africa* lati le fihan pe on ni enia pataki ni igboro Eko ti o si bẹrẹ si ṣata awọn ti ko ṣẹ ti ko ro papa Ọba wa Eleko orin wo ni on papa rope awọn Eko yio kọ k on; tani ko mọ pe ibinu esi ọrọ rẹ ti Ọgbẹni wa Herebert Macaulay fun ninu iwe kekere yẹn (a fẹ mọ loju airan) *Pamphlet of some months* ogo lo nja ranyin ninu ẹẹ ti o si nwa ọna lati le fi gbẹsan lọnakọna, mo rope bi enia ko ba gbagbe ọrọ ana ko ni ri ẹni ba ṣere, njẹ bi awọn ilu ba ni aran kan bi ti awọn ọmọ lẹhin Dokita Randle ṣe nwọn le sọ pe wọn ko fẹ Dokita papa ati Dokita Ọbasa nitoripe nwọn ti sọ ireti nu lọdọ wọn lakoko rogbodiyan owo omi nigbati awọn papa nrafanda lori agba epo ni Ẹnu Ọwa larin gbogbo gbo ilu ti o jẹ pe Kareta ni nwọn nfi bo wọn loju lati le de ipo ọla lọdọ Ijọba, lori gbogbo nkan wọnyi gbogbo ilu jẹjẹ pe pẹlu inudidun ni nwọn fi nreti wọn ni apejọ gẹgẹ bi awọn agbalagba aṣiwaju ti sọ fun wọn pe nwọn nbọ. Dajudaju Dokita Randle pẹlu awọn isangbe rẹ mọ pe nibiti ọpọ enia ba wa nbẹ ni iṣẹgun nbẹ, bi ija kan tilẹ wa ko ha tọ ki awọn agbalagba wọnyi fi ọwọ wọ inu ara wọn lati le fi ayọ pade Arẹmọ Ọba Ilu Oyinbo lọna; bi Ọlọrun ba yan Ọgbẹni Herbert Macaulay lati jẹ amọna ati aṣiwaju kini to ija ati igberaṣanlẹ ninu nkan yi lati ṣo pe awa ko fẹ ri imi rẹ ni atan. Lọna keji "ẹga njale ara rẹ o ni on ntunṣe," a gbọ ti Dokita Randle ti o jẹpe bi ọkọ re okun ti o re ọsa yio f'ori t'elebute nitoripe Dokita nlọ si ilu rẹ ni Saro boya Ọgbẹni P. J. C. Thomas le ni iru ero bẹ lọkan, ewo ni ti awọn enia wa ti nwọn jẹ ọmọ ibilẹ bi Dokita Ọbasa ati Ọgbẹni Darocha ba ro dara-dara nwọn o ri pe ipo wọn gẹgẹ bi ọmọ Eko ju ti awọn ajeji wọnyi lọ, ṣe ọsan to gbe alumọ lọ le tun gbe alumọ pada iyẹn ni pe bi awọn na ba yi iwa wọn pada o le jẹ ifẹ gbogbo ilu lati ti wọn ṣiwaju ninu gbogbo ohun ti nwọn ba nṣe a nja bi ka ku kọ. Awọn agbalagba lo nwipe a ki ṣ'ọrẹ ero ka yọ Ero nre'le rẹ bo dola iyẹn ni ti Dokita Randle ati Ọgbẹni P. J. C. Thomas, nipa ti Lọya Alakija kekere, *ọmọ wa lo jẹ, iyẹn bẹ;* bi Ọgagun Moorhouse tilẹ nfẹ lati tẹ baṣubaṣu tan ki o si ba ara rẹ lọ ilu rẹ ko ha yẹ ki o ye awọn enia ti wa, owe kan sọ wipe oju la fi mọ aisi epo, ẹnu la fi mọ aisi iyọ, ọbẹ ti ko ba ni epo ninu okere lati mọ ọ.

Nipa ti Ọlọla S. H. Pearse ohun ti a le wi ni pe ati jẹ awusa ko dabi ati mu omi, bi a tilẹ ran enia ni iṣẹ ẹru o yẹ ki o ma fi ti ọmọ jẹ, ki ṣe didun ninu wa lati ma ta abuku fun Ọlọla yi oni'le oke Yambari lẹba odo Mosisi nitori na a fẹ ki o mọ pe eyi owu awi ti Ọlọrun Ọba ni yio ṣẹ, ṣe abinu ẹni ko pa kadara da.

Gbogbo wa lo mọ itan Kin-kin ninu alọ, adura wa nipe ki Ọlọrun jọwọ ki o ṣanu fun wa ki ọrọ banta banta yi, papa ọrọ Ọba wa Eleko ko yọri si rere njẹ ara ilu Ẹ ba mi gbe orin alọ yi.

Ọba alaran bẹwẹ kin kin
Obẹ kere ẹiyẹ kin kin
Obẹ kere ẹiyẹ kin kin
Od'emi kin kin si kin kin
Koriko dide kin kin
Eruwa dide kin kin
Ka re'le wa kin kin
Ka re jo bata kin kin
Bi bata o to kin kin
Ka re jo dundun kin kin
Pọnlade pọlade pọn kin kin

Ni ọsẹ to nbọ a o gbidanwo lati la ọrọ kan ye ara wa larin Onigbagbọ ati Imale yala Alufa ti

Onigbagbọ ni tabi ti Imale. "Bi ọwọ ko ba tẹ Eku Ida a ki bere iku ti o pa baba ẹni."

Emi ni tinyin nitotọ,
AKIRIMANU.

## FACTS AND FIGURES.

### A Letter From London.

We are publishing the following extracts from a letter we received last mail from a friend in the interest of our youngmen.

The letter *inter alia* says :—

"By the way, is your intention to tour round Europe still holding? I am dying to meet you here. Travelling is educative and is worth the money and time consumed. But to us Africans a European tour is disastrous. For, born and bred under a foreign government we have been educated to despise our own customs and institutions and regard our masters' as the ideal. With such a temperament we travel into European countries. And, a pity, their vices have more fascination for us than their virtues. As a result, returning home, we try to yoke together two incompatible elements—European and African—and consequently lose our identity or individuality as a nation. In fact what we are, in our *dual state* we ourselves cannot define. There is one name which can be applied to such types of people—*Europeanimaniacs*. This may not be a happy nomenclature, but it can serve practical purposes.................These maniacs are a menace to the nation. They have dangerously polluted the African atmosphere and the mass has been their victim. In language, custom and everything the tendency is to embrace anything European whether good or bad. Why must we wear European dress in an African Country? Why must we speak an odious blend of English and African languages? Or Pidgin English? Even our Education is *English* and *un-African*. The madness of intermarrying with Europeans is another step in the precipitating course. Viewed from an economical as well as racial standpoint, it is most disastrous thing to do. I wonder why our fathers dont remonstrate against such dangerous unions. They are always found inarticulate when circumstances necessitate their shouting from the house-top. It seems they have lost their sway and paternal influence over youth and are afraid to make a public protest. But this matter is not individual but national and hence we need their interference.

In England girls who marry Africans become *Social Outcasts* and I see no reason why boys guilty of such crimes should not be ostracised and made inelligible to have hands in national societies.

But alas, the whole system has run riot.

'Now Roman is to Roman
More hateful than a foe
And the tribunes beard the high
And the fathers grind the low
Therefore men speak not frankly as they did
In the brave days of old'"

This youth is only a specimen of many a Nigeria's son in London who has been fired with genuine patriotism and is anxious that a great deal of useful works is done in the interest and welfare of the race. We cannot but join our esteemed townsman Mr. Henry Carr (in his address to the Union of Nigerian Students) in the hope that when all these young patriots come back home they will not leave behind them in London all the good resolutions they have formed for the promotion of the welfare of our country.

ADEKANBI.

## IROHIN NIPA IGBESI AIYE ATI BIBI OLOGBE

### Muhammed Adewusi Oki

*Ẹniti ofi tlẹ bora ni oṣu December 1924.*

Mahammed Adewusi Oki Oni-saro
Onile-aya-ayo
Ajoshinshin ma da gbese ọkọ "Awa"
Bo kirun, Bo kirun ni ṣo ni Mọṣalaṣi

[ Lati ọwọ ABANIKANDA ]

Muhammed Adewusi Oki jẹ ọmọ Arẹgbẹṣọla Iyankan, Oni-saro nigbati baba rẹ Arẹgbẹṣọla ku ofi ọpọlọpọ ọmọ silẹ awọn pataki ninu wọn ni Brimah Damọle, Agbegilaje ati Ọlabiyi nigbati baba wọn ku ako le rohin gẹgẹ bi wọn ti sinku rẹ nitori aiye gbọ ọrun mọ Allah jeri, wọn si ṣe ẹyọ fun odidi ọjọ meji eyiti ẹnikẹni ko ṣe ri, ti wọn ko si ṣe fun ẹnikẹni ri, ako si ti ri irufẹ lati ọjọ na titi di oni, ninu ẹyọ yi ni ọmọ Arẹgbẹṣọla Brimah Damọle kọrin bayi wipe :—

"Ninu ẹyọ Arẹgbẹṣọla o
"Gbogbo o ṣere ẹba mi yọ
"Sinu ẹyọ Arẹgbẹṣọla"

Gbogbo awọn oloku wọn si fi aṣọ aran ṣe aropalẹ, Brimah Damọle si tun da orin bayi wipe :—

"Ninu ẹyọ Arẹgbẹṣọla
"Awa lafa aran ṣaropalẹ

"Sinu ẹyọ Arẹgbẹṣọla"

Lẹhin orin yi Brimah Damọle tun da orin yi wipe :—

"Eko ko le jẹun
"Ẹgba ko le mumi
"Ijẹbu ko le duro gbo wo Iyọ
"Nijọ ẹyọ Arẹgbẹṣọla"

Nigbati odi ijọ keji ti awọn ẹyọ ndari bọ wa le lati Ẹhin Ọgba (*Victoria Road*) Brimah Damọle si tun kọrin bayi wipe :—

"Ni ijọ ẹyọ Arẹgbẹṣọla
"Gbogbo odun bi ọjọ keji
"Ni jọ ẹyọ Arẹgbẹṣọla"

Nigbati Brimah Damọle papa si ku, ni wọn ọjọ meje, ẹnikẹni ko le wọ ibi ti ogbe ku si afi Adamọ Akẹju (Chief Ọbanikoro) ati Ọlabiyi, eyi fi han nigbana gẹgẹ bi Brimah Damọle ti jẹ akọni enia nigba tirẹ, akoko ko si lati sọ itan nipa Damọle nitori gbogbo yin lẹti gbọ ẹsi mọ pupọ nipa rẹ, Damọle yi ni ọmọ rẹ wa ni ẹhin Mọṣalaṣi Jimọ Belo Damọle ti o wa ni ori akete aisan loni, ki Allah fun ni alafia ara, a ko le sọ itan Agbegilaje fun nyin gẹgẹ bi o ti ṣe ohun ribi-ribi nigbana larin ẹgbẹ ẹbi, ati awọn ẹrẹ.

Ka tun wa sọ ti Ologbe Muhammed Adewusi Oki gẹgẹ bi awọn Oloye Ọbanikoro ti nfa oku yi mọ Oloye Aṣogbọn lọwọ ati larin Imam Jamiu Ligali ati Noibi Tijani to nkirun fun awọn janma Ọbanikoro nipa ki kirun si oku yi lara nigbati oku de itẹ ki Imam Jamiu Ligali to de, Nọibi ti fo fẹrẹ o ti kirun si lara ṣugbọn igbati Imam Jamiu de o wa kirun si lara eyiti gbogbo awọn janma ati awọn ti Nọibi pẹlu rẹ, ijapari amọ nkankan daju wipe tị ko ba si ipo ti tiu wa oku Adewusi Oki oku Ọba lo jẹ.

Adupẹ lọwọ awọn Oloye oni fila funfun, Oloye Eletu Odibo, Oluwa, Aṣogbọn ati Obanikoro nwọn la dabua nibi oku Muhammed Adewusi Oki, ọmọ oloku ti oruko rẹ njẹ Yesufu Adeọla Oki o jẹ akọbi ọkunrin Ologbe ti o si jẹ Akọwe Loya Shyngle (Ẹbọra nile ẹjọ) fun gbogbo asiko ti wọn fi sin oku yi ọna owo, onjẹ pe onjẹ ranṣẹ ṣugbọn ko si *Lemonade* oni tẹrọ nibẹ de ibi ti o ma ri oriṣiriṣi ọti, ṣugbọn esi rẹ ni Ahmadia ki mu ọti (bẹni Ahmadia ko ni ki wọn ma fi ṣe alejo gẹgẹ bi ati gbọ) esin ṭa nipa pupọ ki ṣe wipe owo rẹ ko si igbagbo yi le.

Aki gbogbo awọn ọmọ oloku pataki, awọn bi Alhaji Damọle, Sanni Damọle (Bọrọda agba) fun onjẹ, *Cigar* ati ọpọlọpọ anya, gbogbo agbo ile Layẹni ati awọn Adeṣigbin, Chief Aṣogbọn, Iya alin Fọwọbọla Ibitẹso, Belo Damọle ati Ogbẹni L. E. Abraham ẹniti ojẹ ọrẹ papa ti Ologbe yi. A ki nyin ati ẹnyin ti ẹ wa ti ẹ kọwe ranṣẹ ẹ ṣe pupọ.

Ni ọsẹ ọla ijọ kẹdọgbọn oṣu yi ni awọn ọmọ oloku ma kasẹ oku ni lẹ ogoji ọjọ, nitorina gbogbo enia la pe wa fun ọjọ na. *All are cordially invited—No Invitation Cards. Whether Christian, Pagan or Mohammedan*

*Thanking you Mr. Editor for space allowed.*

Emi ni tiyin nitotọ,
ABANIKANDA.

---

## IN MEMORIAM.

"KOSI'UNJỌ'YA."

In ever loving and affectionate memory of our dearly beloved mother
RACHAEL ỌṢUNTUKẸ
who departed this life on Sunday 19th January 1908.

Tho' 17 years have passed,
Yet we feel her absence every hour.
*R.I.P.*

D. A. BECKLEY
*and Family.*

Wesleyan Mission House,
Ago, via Ijebu Ode.

---

## IN MEMORIAM.

In loving memory of our dearly beloved Father
DAVID ADEṢIYAN GANSALLO
Who entered into rest on the 27th of January, 1924.

"This life of mortal breath
Is but a journey,
To the life Elysian
Whose portals we call death"
*Longfellow.*

ADEOYE GANSALLO,
YETUNDE GANSALLO.

## *Register Now!*

For the evening classes now forming at the Rose Thomas School of Embroidery, 55, Broad Street, we teach :—

Embroidery, Milinery, Flower Making, Fancy Work, Dress Making.

5 week days, Monday to Friday—from 2 p.m. to 6 p.m.

*Price 2/- per week.*

The West African Soap Co. Limited
APAPA, NIGERIA

*Manufacturers of*

NEPTUNE
PALE SOAP

BUGLE
PALE SOAP

MAGNET
CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

P.O. Box 522
Lagos
Nigeria

P 303


## Thanks For Sympathy.

Mr. J. S. Andre, on behalf of himself and family begs to return his sincerest thanks to all those who called or otherwise sympathised with him, in the loss sustained by the death of his dearly beloved father SALAKỌ ANDRE, which occured at Agoueh on the 30th ultimo.


GBADAMỌSI BIṢI NPE NYIN
Ẹ WA, Ẹ WA !

Gbadamọsi Bişi olorin ọlohun iyọ jẹ onişegun Ema Dudu, o si ni orişirişi egbogi iwosan, papa fun arun ti o nja l'ode nisinsinyi.

Orukọ Olodumare nikan lo nsà ninu egbogi yi.

Ẹ lọ dan a wo ni'le rẹ̀
ni 3, Palm Church Street
Idi Iyeyè
Itafaji
Eko.

## White's Golden Male Tonic.

(DOUBLE-STRENGTH)

Whenever a women has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs. Now while it is true that many women suffer from disease yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. *White's Golden Male Tonic* (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

**Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

*The Reliable Dispensary, 41 Offin Road, Lagos.*

N.B. NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.

**SHAKE THE BOTTLE**

AREMỌ FUN ỌKUNRIN

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo Arun ti ki jẹ ki okunrin şe abiamọ.

N.B.—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo mejimeji loşoşu—Işẹ ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

**Price ten shillings ( 10/- ) per bottle.**

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, JAN. 24, 1925.

## ĘJỌ WA JARE, GBANGBA
## ĘJỌ WA JARE, GBANGBA.!
## NWỌN FUN WA LARE, GBANGBA!!
## NWỌN FUN WA LARE GBANGBA!!!

Orin t'o yẹ t' ọmọde t' agba awọn Jamma Musulumi l'ọsẹ yi l'eyi nitori Idajọ ribiribi ti awọn ogunna gbogbo Adajọ Kotu Arotunro (*Appeal Court*) ani awọn Adajọ *Sir* Ralph Combe, Adajọ-Agba, ti o si tun jẹ Alaga Kotu Ganran, M. L. Tew Ọlọla ati T. W. Maxwell Ọlọla da lana nipa ti ọrọ ẹjọ Mọṣalasi nla ti awọn Ilu pe awọn "Koṣeyọ" eyini ni ijọ ti awọn Alli Balogun.

Ẹnyin Ọkawe wa yio ṣakiyesi pe ẹjọ yi ti bi Ige, o si ti bi Adubi lọjọ pupọ sẹhin ki *Sir* F. A. Vander Meulen, Adele Adajọ-Agba, Akere-koro, to fi Ake ofin ke ni Alamisi ogunjọ oṣu *March* l'ọdun tokọja nipa dida are fun awọn Ilu, ti konko pọun mẹtadinlogọjọ, ṣile mẹwa (*150 guineas*) fi ru awọn "ara 'le wa" gẹgẹbi o ti wa ninu Iwe Idajọ na, eyiti apele rẹ njẹ *Suit No. 8 of 1924*:—

1. Pe awọn Janma jare ẹjọ ti nwọn pe Tijani Naibi ati awọn enia rẹ

2. Pe Tijani Naibi na ati awọn ẹgbẹ rẹ ko gbọdọ mọ l'ẹwa, ki nwọn yan run lati oni lọ lati tun lọ yọ awọn Janma lẹnu ni Mọṣalaṣi nla na, ṣugbọn ko sọ pe ki nwọn ma lo kirun po nibẹ o, ẹla l'ọrọ.

3. Pe gẹgẹbi o ti jẹ pe Lemọmu-Agba kan lo yẹ ni'lu fun olori Mọṣalaṣi, Kotu gba Lemọmu Lagali gẹgẹbi Lemọmu-Agba ti gbogbo awọn Janma f'ohun-ṣọkan yan.

4. Pe ki a ṣi Mọṣalaṣi nla na ti Tijani Naibi ti fi ọna abosi ti lẹsẹkẹsẹ.

5. Pe ki a ko gbogbo kọkọrọ Mọṣalaṣi na fun Lemọmu Abasi olori awọn Ratibi (Ọgbẹni yi jẹ ọkan ninu awọn Janma ti o p'ẹjọ) ki Lemọmu na si ma wa labẹ aṣẹ ohun ti gbogbo Janma ba fi ohun ṣọkan si ni ṣiṣe nipa ti Mọṣalaṣi na.

6. Pe Tijani Naibi ati awọn ẹmẹwa rẹ jẹbi ẹjọ ti awọn Janma pe wọn.

7. Pe Lemọmu Ligali ni Kotu gba ni Lemọmu Agbà dipo Lemọmu Braimah (Ologbe) ati pe oye Lemọmu Agba ti awọn kan fi Tijani Naibi jẹ, jẹ oye abosi, ti nwọn da lọ jẹ ni ikọlẹ.

Ẹ o tun ṣe iranti pe nigbana "*Eko Akete*" pẹlu Atari Ajanaku lo kọkọ tan irohin ayọ yi rẹrẹ bi ẹjinrin fun gbogbo agbaiye lati ka nipa Iwe Akanṣe ti a kọ sinu rẹ ni ọjọ kejilelogun oṣu *March 1924* ti a fi kọ akọle rẹ bayi:—

Ọjọ a ba pade l'ẹhin ọgba,
Kúgú a fọ́ lẹhin ọgbà.

Laifi ṣe ètè lọṣọ, "*Eko Akete*" ti a tẹ nigbana jẹ ẹ̀dẹ́gbẹ̀jọ (1,500) ni ọjọ Satide na, o si tan bi adiẹ ko sọ'ka ki o to to irọlẹ alẹ *Monday* ti o tẹle.

Ṣugbọn nigbati a si tun gbọ pe awọn ara wọnyi tun fẹ iya jijẹ kun—a pe ni iya, nitori ko si onilakaye enia ti o ma ka Iwe Idajọ ti Adele Adajọ Agba kọ, ti o si ka fun ara rẹ niwọn lile ni wakati kan, ti Ọgbẹni E. A. Marsh, a-l'oni-gbese-du-bià-bià tú pẹrẹ-pẹrẹ rẹ nipa ṣiṣe ogbufọ Adele Adajọ ni ede wa, ti ki yio wipe alaṣeju ti np'ọkọ ni baba nikan ni Iwe Idajọ na ko tẹ lọrun.

Ṣugbọn o dabi ẹnipe awọn ara wọnyi fẹ mu owe Yoruba ṣẹ pe "bi ṣigidi ba ma tẹ a ni ki nwọn gbe on s'ojo" nipa gbigbe ẹjọ na lọ si Kotu Onidajọ Mẹta tabi Kotu Alarotunro-Ẹjọ (*Appeal Court*). Ninu oṣu *December* ni *Lawyer* awọn Janma ani *Lawyer* Latunde Johnson, ọkọnrin jọgọlọ-kòrò-janjan, fi pẹki kan pẹki pẹlu *Lawyer* Ajasa ti o jẹ *Lawyer* awọn ti a akeji; kosi si ẹniti o wa ni kotu *Appeal* yi ni gbogbo akoko ti ẹjọ na gba ti ko ni ri bi *Lawyer* Latunde Johnson ti nhan iyàgbẹ́ bi ẹiyẹ ibákà mọ ọrọ tabi ijiyan ti *Lawyer* Ajasa nfi kõ loju; nigbati awa pãpã si ri bi *Lawyer* "Ọmọ Ọba" yi ti nfi lakaye ṣe àgbèkà ọrọ tirẹ niwaju awọn Olotu ofin mẹtẹta wọnyi, a ni tanmọ nigbana pe bi ilẹ

ko ba pa enia da, bi a ti ba oni, bẹ la o ba ola; njẹ a bere ẹnyin ọkawe wa, o ri bẹ tabi ko ri bẹ ?

Bẹ lo ri faufau, ikǫ kò kǫ ejo lẹsẹ, oku ni ẹlẹja nta lori atẹ ni'ta Faji, tani j'enia. Agbo meji ko mu'mi l'akoto! Abọ oko aje ti awọn apakeji lọ kọ yi ndan ? Tabi nwọn tun fẹ fi owo nwọn gbagi si i nipa titun gbe ẹjọ na lọ si abẹ ẹsẹ Ọba King ni'lu Oyinbo (*Privy Council*) nwọn ṣa ti j'oye "*Never tire*" bi àṣà ọrọ iwāsu ọrẹ wa kin? Ṣugbọn ki a ma ti ṣāju ẹlẹdẹ.

Njẹ nisinsinyi ti ara rọ Wòrú l'oko ọfà, ko ha yẹ ki nwọn jẹ ki ilu fi ẹdọ lori òrorò bi ?

Awọn ēgun ofin mẹta ti nwọn fọhun bi enia lana tun kirin Idajọ Adele Adajọ Agba lẹhin pe bi o ti kọkọ da ẹjọ na si bẹni awọn pāpā ri si, ati pe ki awọn ti ẹrù pa na tun lọ san pọnun mejilelogoji (40 *guineas*) owo irin esẹ fun awọn Janma.

Adajọ Agba (*His Honour* Sir Ralph Combe Knt.) ati Adajọ M. L. Tew Ọlọla lo gbe ọ̀pẹ̀lẹ̀ Idajọ Apili yi ṣanlẹ nipa kika ọrọ Idajọ na, eyiti o gba wọn ni iṣẹju mẹdogun, eyini ni lati agogo mẹsan āro àna gān titi o fi de agogo mẹsan fi iṣẹju mẹdogun kọja.

Lẹhin eyini ni Adajọ Agba wi fun Ọgbẹni G. Adeyẹmi Wilson, gbedegbẹyọ olohun oyinmọmọ ti Ganran pe ki o sọ fun awọn Janma pe bi Adele Adajọ Sir F. A. Vander Meulen ti dajọ na si l'akọkọ bẹ̄ gan ni awọn papa tun da; ọgafa ilẹ bẹrẹ si rọ nigbati gbogbo enia ṣi pī bi ogun, ti nwọn si kuro ni Kotu. Ariwo sọ lala nigbati awọn Janma nfi ayọ lọ sile.

Awọn Ọlọpa dẹ ati awọn Oyinbo Olori Ọlọpa wa nibẹ pe ki o ma si ija tabi ita kan ko si si ọrun to jọ bẹ̄.

A ba ẹnyin Janma yọ fun iṣẹgun nla yi; eyi fi han gedegbe pe ẹ̀tọ́ ati ṣẹ̀ria lẹ ti mba bọ lati ẹhin wa; ṣugbọn a fẹ ṣe nyin ni kilọkilọ kan, ki a maṣe ri ọkan ninu nyin tabi ninu awọn ọmọ nyin ti yio ma k'ọrin ēbu tabi sọrọ ēbu si awọn ti ẹsin nwọn ṣẹ'sẹ ninu ere ẹjọ yi. A ko ni ki e maṣe yọ bẹkọ; *Allah* lo ni k'ẹ yọ, ki ẹ si yọ ki ẹ fi ogo fun Ọbangiji Ọba Sòkó ki ẹ si fa awọn ọmọ nyin ti nwọn fi iyaju ba nyin lo lati ọjọ jọjọ yi mọra, ti nwọn ba tunba ki ẹ si tun wa ni irẹpọ lẹkansi bi ti atẹhinwa. Imọran bayi ni Sir F. A. Vander Meulen gba nyin ni jelo nigbati ẹ jare lakọkọ. Ẹ ki yio ha mu imọran rẹ ṣe bi? O d'ọwọ Ọba Oke pẹlu.

A si tun dupẹ ẹmi nyin ti a dasi lati tun ri asẹhinwa, asẹhinbọ Apili yi.

Ẹ jare ẹ ba ni gbe wákà yi ni agbe-gba-dun :—

Anọbi o gbọwọ ilu o,
Ẹ ṣ'amin, amin, amin a, ẹ ṣ'amin,
Amin, amin a, ẹ ṣ'amin
Boya Malaika a jẹ ṣ'amin,
Boya Malaika a jẹ ṣ'amin,
Alhamdu lilahi !!!

---

## GLOVER MEMORIAL HALL.

[ *Lati ọwọ* ATARI-AJANAKU. ]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ l'oji,

Ijọba Gẹsi ti de si Eko ni akoko Ọbo Dosu-mu. oniruru Gomina ni o si nwa jẹ Ọba l'ori wa lati Ilu Oyinbo, gẹgẹ bi Aṣoju-ọba Ilu Gẹsi. Gomina miran, ẹrú Ọlọrun: omiran, ọta Ọlọrun; ilu r'oju ni akoko ti ẹlomiran ninu wọn, : o si daru ni akoko ti ẹlomiran; ẹniti ko ni ile ri, di ẹniti o ni meji, mẹta tabi ju bẹ lọ ni akoko Gomina miran : ati ni akoko Gomina miran, ẹwẹ, ẹniti o nfi ile mogeji (*mortgage*) fun Owo-èlé, asinwa-asinbọ, Oni-gbanjo yio ta ile na mọ ọ l'ori!

Ohun iyanujẹ ni, ti akoko Gomina miran ba to lati fi wa silẹ lọ patapata: ọro ayọ nlánlà si ni, ti Gomina miran ba ko ori buruku rẹ lọ kuro li arin wa. Awa Enia Dudu ko nṣe Igi, a ko nṣe Ọpẹ, bẹni a ko si nṣe Aṣiwere; Gomina ti o ba ṣe rere fun wa, a o sure fun u: eyiti o ba si ṣe wa ni ikà, a o ke "Tàbátiada" le e l'ori!

Gomina miran a de, yio sọ wipe on nfẹ ki Oyinbo ki o wa li ọtọ, ki Enia Dudu ki o wa li ọtọ (*Segregation*,) ki awon mejeji ma si ṣe sunmọ itosi ara wọn. Nigbakigba ti a ba si nri ofin, tabi aṣẹ, tabi ifẹkufẹ oni-kanmọ bayi kà, ẹrin ṣa ni o ma nwa si ẹnu wa; nitori, ero tiwa ni wipe, Ọlọrun papa ti fi alagbalugbu omi okun palà si arin awa pẹlu Oyinbo, Oyinbo ti ko ba si fẹ lati ri Enia Dudu s'oju, o san pupọ ki o kuku joko si ilu

rẹ, ki o ma ṣ'agbe-jẹun, ju ki o wa si ilẹ yi lọ, ki o si ma sọ isọkuso wipe, on fẹ ki Oyinbo wa li ọtọ, ki Enia Dudu wa li ọtọ; tal'o ranṣẹ si i wipe ki o ma bọ ni ilẹ yi?

Bi awọn Oyinbo tabi Gomina miran si ti fẹ *Segregation* tõ ni, Kúkù (*Cook*) Enia Dudu ni o nse onjẹ fun wọn, *Steward* Enia Dudu ni Agb'awo wọn, adiẹ ti Enia Dudu nta ni nwọn njẹ: Enia Dudu ni Akọwe wọn; ninu Owo-epo, Owò-ekurọ, Owo-kòkó Enia Dudu ni nwọn njẹ; sibẹsibẹ, nwọn ni awọn ko fẹ Enia Dudu ni sakãni awọn. —A-da-bi!

Elomiran le wipe, ọrọ *Glover Memorial Hall* ni a kọ si oke Iwe yi, ati wipe, nitorina, kil'o kan ọrọ Gomina ko-ṣe-Gomina nibẹ? Bẹni! Ọrọ l'o ba mo kó, mo rò wa! A ko le sọ ọrọ Ile-ẹgbẹ Ehingbẹti yi l'ai daruko *Governor* Glover, tabi Gomina ti awọn agbalagba npe ni "Goloba," ni iranti ẹniti ilu kọ Ile nla na si Ẹhingbẹti.

A ko sọ wipe, Maleka ni Gomina Goloba nṣe; ṣugbọn, ibaṣe wipe iwa tirẹ dabi ti diẹ ninu awọn Gomina miran ti awa ka si Ko-kewu-ko-bere, boya a ki ba ti kọ́ ju Ile-ọpa ọl'ọgọrun pọnwun si Yaba ni iranti rẹ!

Ṣugbọn, ọmọ'luwabi ni Goloba nṣe, o fẹran ọmọde, o fẹran agbalagba, ko si mọ iyatọ li arin Oyinbo pẹlu Enia Dudu! Bi gbogbo Eko tilẹ gbagbe inu-rere rẹ, awọn ti o fun u ni ilẹ lati kọ ile a ha jẹ gbagbe olõre wọn; tabí, ẹrú, ọmọ, ati ọmọ-ọmọ Oṣodi wo ni o le gbagbe *Governor* Glover?

Iwe ti Iyawo rẹ, *Lady* Glover ṣe nipa baba wọn, ani, Iwe ti Ade Oṣodi ka si pataki julọ ninu ohun iṣura rẹ ni ko tõ tun ni, (gẹgẹ bi àṣa Ẹgba,) tabi, Ipò ọlá ti *Governor* Glover pãpa gbe *Chief* Oṣodi de, ni ko tõ yẹ-si?

Ẹ ngbọ "Hector Latunde Glover," Glover ha nṣe oruko Tapa bi? Agbẹdọ! Ṣugbọn, ẹmí imõre idile Oṣodi ni o jẹ ki nwọn gbe oruko olõre wọn ka'ri, eyini si san lọpọlọpọ ju ti ọgọrọ Enia Dudu ti o njẹ orukọ Oyinbo l'ainidi lọ!

Lati le ṣe iranti ti o jo'ju fun "Goloba," ilu pinnu lati kọ Gbọngọn (*Hall*) nla kan si Ẹhingbẹti, eyiti a o ma pe orukọ rẹ ni *Glover Memorial Hall*. Kiriyo, Musulumi, ọmọde, agba, ọkunrin, obirin, gbogbo wọn ni o parapọ ṣe ko-kari Gbọngan na. A mo ẹniti baba rẹ da owo ribiribi si kikọ ile na, a mo ẹniti baba rẹ da diẹ, a si mọ ẹniti baba rẹ ko ri bọ tara li akoko na, de ipo ti yiò le da Kọbọ kan sinu rẹ; a si tanma wipe, ipo-ki-'po ti o wu ki iru awọn ọmọ mẹkunnu baba bẹ le wa loni, nwọn mọ ara wọn gẹgẹ bi awa ti mọ wọn!

Lẹhin ti Ile na pari tan, a ṣi i fun lilo ilu, a si yan Olutọju (*Trustees*) fun u, li ọna ti ofin yọda. Bi Olutọju kan ba pa ipo da, ẹlomiran yio dipo rẹ, bẹni o si ṣe titi o fi bọ si ọwọ awọn ti o nṣe olutọju rẹ nisisiyi, awọn olutọju ti Ọlọla S. H. Pearse nṣe Akọwe (Sẹkitẹri) fun.

Bi ẹnikan fẹ ṣe ere, tabi ti o fẹ ṣe Ipade ni Ile-ẹgbẹ yi, o ni lati gba aṣẹ lọwọ awọn Olutọju, o si ni iye owo ti oluwarẹ na ni lati san. Nitoripe, bi Ile na ba nfẹ a-tun-ṣe, owo ni a o fi tun u ṣe, eyi ni ko si le jẹ ki a wipe, o yẹ ki ẹnikẹni ma lo Ile na li ọfẹ; ṣugbọn nitorina, owo ti awọn Olutọju ngba nisisiyi fun hihaya Ile na lati lo fun wakati meji tabi mẹta li ọsan tabi li oru, o pọ pupọ ju, papa, nigbati ko nṣe wipe a kọ *Glover Memorial Hall* na lati ma fi ṣe Owò (*Commercial Enterprise.*)

Iṣiro gbogbo owo ti nwọn ngba nibẹ, ati eyiti nwọn nná le e lori ni nwọn nṣe Iwe rẹ, ti *Auditor*, ẹniti o ntu Iṣiro-owo palẹ, ti o si nfi ọwọ si i nigbakugba.

Ṣugbọn, bi o ti jẹ wipe, Ile ti ilu kọ ni, o yẹ ki awọn Olutọju ma tẹ Iṣiro na sinu Iwe-irohin Ọba *The Nigerian Gazette*, ati Iwe-irohin ilu, bi *Record*, *Pioneer*, *Messenger*, *Eko Akete*, *Spectator*, *Eleti-Ofe* ati *Advocate*, fun gbogbo ilu lati ri i ka, ki a le mọ bi nkan ti nlọ si gãn, bi ère ni nwọn njẹ lori Ile na ni, tabi adanu ni nwọn npa.

Eyikeyi ti o wu ki o jẹ nibẹ, a ri oye diẹ nipa bi apo awọn Olutọju ti fuyẹ to, ki a to da Ẹgbẹ Tunluṣe (*The Nigeria National Democratic Party*) silẹ, a si mọ bi apo wọn ti wuwo to lati igbati a ti da Ẹgbẹ nla yi silẹ.

Gbogbo Ipade-ẹgbẹ Tunluṣe ti a nṣe nibẹ ni a nsan owo fun; ṣugbọn, nigbati a ri iro gbọ wipe, Arẹmọ-ọba Ilu Oyinbo nbọ, nwọn kọ Iwe si Ọlọla S. H. Pearse wipe ki o sọ fun awọn ẹgbẹ rẹ, ki nwọn yọda Ipade ọfẹ nigbakugba ti a ba pejọ sibẹ lati ṣe aṣaro ọna ti a o gba ṣe iyẹsi ti o to iyẹsi fun Arẹmọ-ọba: Pearse si fesi wipe, awọn yoda.

Owo ti awọn Olutọju ti ngba ri fun hihaya Ile-ẹgbẹ li Ebute ni a sọ wipe o pọju yi, ṣugbọn ni atalata ijejila, lẹhin ti awọn ọmọ ẹhin Dokita Randle ti lọ fi ara wọn jẹ oye si apo ara wọn ni ile Colonel Moorhouse tan, awọn olutọju tabi *Trustees Glover Memorial Hall* ṣe ipade kan larin ara wọn nijọna gan, nwọn si pinnu pe ẹnikẹni ti o ba fẹ ṣe ipade gbogbogbo (*Mass Meeting.*) ni ile Ẹgbẹ ehingbẹti, o ni lati san pọun mẹjọ, ṣile mẹjọ.—*eight guineas.*

Loya I. T. Nelson Cole ọkan ninu awọn olutọju Ile yi ati Ọgbẹni C. W. George ọmọ ologbe Ọṣọba *The Honourable* C. J. George J.P. ọmọ ẹniti o da ọgọrun pọun £100 si owo ti nwọn fi kọ Ile ẹgbẹ na, wipe pọun mẹjọ ṣile mejọ pọju, ṣugbọn awọn yoku na wọ soke pe owo na ko pọju. Ẹniti Baba rẹ da ọgọrun pọnwun nsọro, awọn ara ile wa ngbọ o l'ẹnu; ngbọ, aiye sa ti di aiye Oyinbo, ẹru ntọngadi ọmọ.

Nigbati o ṣe pe ọrọ ire Ilu ni a nsọ ni ipade gbogbogbo, to si ṣe pe afi bi a san pọnwn mẹjọ ṣile mẹjọ ki a to le pejọ si Ile ti a fi owo Ilu kọ, igi ko ha da baun? *Well*, awọn olutọju ti ṣe ipinnu ti wọn na, iyoku ku si ọwọ wa. O yẹ ki Ilu ṣe apejo nla, ki nwọn si ko ipinnu wọn lọ ba Ọlọla Loya Shyngle, Ọlọla Loya Moore ati

Dokita Jones pe ki awọn mẹtẹta ko iwe si awọn *Trustees* olutọju *Glover Hall* pe ki nwọn din owo ti bu kọja idaji fun wa, bi awọn ba si kọ, o yẹ ki a pe nwọn l'ẹjọ si Kotu, ki wọn wa sọ idi rẹ ti wọn ki yio fi din owo na ku.

Nigbati nwọn sọ di pọnun mẹjọ ṣile mẹjọ yi ti a ba nsan owo na lati le ṣe ipade nibẹ, ki a to ṣe Ipade meji, nwọn tun le sọ di ogun pọnwun ogun ṣile fun Ipade kọkan.

Awọn to wo ṣunṣun ti nwọn sọ owo Ipade kan di pọnwn mẹjọ ṣile mẹjọ bayi nwọn ṣebi owo nso si ẹhinkule *Glover Hall* ni ti enia nri kan abi nwọn tilẹ fẹ sọ ile na di ahoro ki ẹnikẹni, otale lo o mọ? Eyikeyi ti o wu ki o jẹ nibẹ, awa tanma pe nibiti Governor Glover papa wa loni, o le gbọ pe awọn ti Ile ti a kọ ni iranti on wa labẹ ojo rẹ sọ ipade kan ninu Ile na di pọnwun mẹjọ ṣile mẹjọ, epe ni yio ṣẹ fun gbogbo awọn to lọwọ ninu rẹ, ti nwọn si fẹ fi orukọ on gbona, nitorina a ko le pe orukọ Ile Ẹgbẹ ẹhingbẹti na laipe orukọ on "Goloba."

Nitoto, ẹniti ko ni ga, ti ko ni go, ko kọ ki ogun ja Ilu.

APILI ( *APPEAL* ) Ṣ'OJU ẸMI.

Nigbati awọn ara ile wa ni nwọn fẹ ja aja-igbula lọ si Kotu Onidajọ Mẹta nijelo, a kilọ fun wọn titi pe adẹtẹ ko le wa ẹkọ mu, ṣugbọn nwọn ṣe, ti gbọnin s'ẹbọ, nwọn ṣe agbọran s'eṣu; asiuwa asiko, nwọn tun jẹbi l'ekeji, Kotu si bu pọnmejile-logoji fun wọn ni sisan gẹgẹ bi owo irin ẹsẹ.

Ọrọ Apili awọn Alli Balogun ni a nsọ, nigbati awọn ni Lemọmu Ligali ọlohun iyọ ko tẹ wọn l'orun.

Ki Kotu to ṣe idajọ l'arọ ana, ni pupọ ninu awọn Musulumi apakeji ti nsọ wipe Afa Tijani lo ma jare, ṣugbọn kẹkẹ p'ohun mọ awoko lenu nigbati nwọn ri pe Lemọmu Ligani ni Kotu Onidajọ Mẹta tun gbe gun ori oye.

Idajọ yi ko ya ẹnikẹni lẹnu, nitori loju tiwa, ẹjọ awọn Alli Balogun ti jẹbi gbangba ki nwọn to kuro nile; sibẹsibẹ a ni lati ki wọn ku ewu, a ni lati ba wọn yọ ayọ nla, nitoripe bi o ṣe pe awọn lo jare ni, laisi ani-ani, are na iba di ẹti si wọn lọrun; nibo ni nwọn iba si ru u wo. Ani, bi awọn Alli Balogun jare, are na iba dabi enipe nwọn gbe awọn odo mi ni, ti iduro ko si, ti ibẹrẹ ko si, ti ijoko ko si, ti idubalẹ ko si, nibo ni nwọn iba ru u wo?

Aye ko si fun wa to ni ọsẹ yi lati sọ ọrọ Apili yi ni talanda, ṣugbọn nigbati awọn Alli Balogun san adọjọ pọnwun, adọjọ ṣile gẹgẹ bi owo irin ẹsẹ nijelo, ti nwọn tun ni lati san pọun mejilelogoji gẹgẹ bi owo irinẹsẹ l'otẹ yi, laika owo ti nwọn ti na fun Loya t wọn papa ati inawo orişirişi miran, ona alọ Ijapa t roko ọkọ yanrinbo kan ni a to pe o le kọ si gbogbo inawo ainidi nwọnyi. Nitorina, ti a ba nwipe "Ajapa," ki ẹ ma dahun pe "Rẹpẹtẹ."

Rẹpẹtẹ o, Ajapa o.
Kilọ ma ta, sanwo rẹpẹtẹ. Ani Rẹpẹtẹ, Ajapa o.
Kilọ ma ta sanwo rẹpẹtẹ.

Ki Baba jẹ ki ilu r'oju, ki O si fi aya ilu balẹ, ki gbogbo wa le jumọ fi inu didun ati ayọ nla pade Arẹmọ Ọba Ilu Oyinbo. *God save the King!*

Emi ni tinyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

# EKO EKETE
## LAW REPORT

IROHIN ILE ẸJỌ ỌLỌPA NIWAJU ỌGBẸNI H. S. BERKELEY.

[ Lati ọwọ Atolugbokun. ]

### "BOBA RI AJA EWULỌ KO KI"

Ni ijọ keje oşu yi ni ọlọpa ra kurumọ kan mu ti orukọ rẹ nje John Bassey ti Ijọba fi ẹsun wipe o fẹ iganna ninu iti mọle lati sa lọ. Loya Onọtaku Thompson lowa fun ọdaran yi. Loya Thompson bẹ Adajọ o si wipe ki Ijọba fi eyi fa leti nitori ọdaran yi ti wa ninu iti mọle lati ijọ marundiladọta ni ọgba ẹwọn nitori na eyi to ibawi fun. Agbẹjọro Ọba ni ti ko ba si ti ọgbẹni Fọla Sapara to ra ọdaran yi mu nigbati o nsa lọ ọdaran yi ko ba lọ bamubamu Adajọ ni on fi eyi fa leti ko ma lọ.

### "ỌRỌ ỌLỌRỌ LAFI NṢE ARI KỌGBỌN"

Ni ijọ keje oşu yi ni ọlọpa ra awọn ẹlẹgiri meji Kurumọ mu ekini "George Washington ekeji Jackson nşişẹ ninu ọkọ S. S. *Benue* ni ijọ keje oşu yi ni ekeji Jackson lọ si ninu ọkọ nigbati Jackson si bọlẹ ninu ọkọ George Washington fun ni igo ọti Gini kan ( *one bottle Geneva Gin* ) nigbati Jackson fẹ kọja ni ẹnu Bode Ọlọpa ni ifura si o si tu lara wo nibẹ lo gbe ri Oti ti Jackson gbe pọn, rẹrẹ odi ọgba Ọlọpa, nibiti awọn Ọlọpa gbe wa di oro yi. Ọga Ọkọ ni ogoji Oti ni awọn gbewiri ti pọn jade, ṣugbọn Ọkọ na wa ni ikoja Gambia nigbati ẹjọ yi wa si kotu ati pe a to ipari oşu ki Ọkọ to tun pada de bi nitorina awọn Ọlọpa ko ro'jọ pẹlu wọn mọ ( *we are asking for discharge under section 68.* ) ati pe ẹjọ yi tiwa ni iwọn ọsẹ pupọ-Adajọ ni ki wọn ma lọ.

### "ERI LAWẸ—AKI WẸ IRIRA"

Ni ijọ *Wednesday* ijọ kẹrinla oşu yi ni ẹjọ olori agbawo ( *Chief Steward* ) ile Ọba ( *Govt. House* ) ni Eko wa si iwaju Adajọ tun ẹsun wipe *Tea Pots, Tea Cups,, Bed Sheets* ti o jẹ ti Ọba, ọdaran yi ni

on ko jẹbi. Ọrọ ọdaran yi ko pọ. Oni odi odidi ọdun mẹrindilogun ti on ti wa ni ile Ọba gẹgẹ bi Olori agbọti nkan wọnyi iyara on lowa on ko ji, oni kọ loti wa ni yara on. gbogbo awọn Oyinbo lo ri ni ori tabili on, ati pe bi awọn ọrẹ on ba wa si ọdọ on ni ile Ọba, on ayọ *Tea* fun wọn nipa *Bed Sheets* on fun ra on loni yẹn. Sẹkitẹri Ọba ni Tom yi ti wa nibiṣẹ pẹ ṣugbọn ko ni aṣẹ ati ko nkan yi si iyara rẹ. Adajọ ni on ri wipe o jẹbi. Sẹkitẹri Ọba ni Ọba ni ki on sọfun wipe ko fi eyi kọ awọn Agbawo yoku lọgbọn. Adajọ ni o dara ko lọ si ẹwọn oṣu kan pẹlu iṣẹ aṣegan Ibi ti iṣẹ ọdun mẹrindilogun Tom gbe pari si re o!

## "ẸRAN ILE—LO NFI OJU DI ỌDẸ"

Ni ijọ *Friday* ijọ kẹrindilogun oṣu yi, ni ọlọpa mu akọwe Lọya S. B. Rhodes wa si ile ẹjọ fun ẹsun wipe o lu ọdọmọbirin kan ti oruko rẹ njẹ Ọlawunmi ti o ngbe Forsythe Street ni Eko. Oruko akọwe yi njẹ Titus Folaranmi-Ọlawunmi ni akọwe yi fẹ fẹ on, on si gba, o wa ranṣẹ wipe ki on fi oju kan on, on kosi ri aye lati jẹ ipe rẹ, nigbati on nkiri ọja ti on nta, ni ọdaran yi wa ba on, pe no ranṣẹ pe ẹ o ko wa, o bẹrẹ si on lu. Ọlọpa ti oruko rẹ njẹ Mrsa Idah A 938 ni ibiti akọwe yi r lu ni on gba a; akọwe yi ni ko ju ki on san owo lọ. Adajọ bi bo lu, o ni on ko lu. Adajọ ni ko san ṣile meji abọ. Ti wọn ba tun mu wa on a kọ lọgbọn. bi Titus Fọlaranmi yi ti kuro ninu ẹgiran to duro si ni Ọgbẹni Reis ti awọn Ọlọpa pe wipe ko ye yọ ọmọ on lẹnu. Ti ko ba ye yọ lẹnu yio di ọran si lọrun nitori ọmọ on ṣi nkọ iwe ni o Titus ẹsọ ko to ọ.

## "NIWAJU ỌLỌPA M. L. TEW NI KOTU NLA"

"*Judgment Summons*—Ẹjọ Onigbese"

Larin Peter John Claudius Thomas ati Florentius Severino. Ni ijọ *Monday* ijọ kọkandilogun ni ẹjọ yi wa siwaju ile Ẹjọ. Ọgbẹni Lọya Taylor (Egun-bi-ele) lo wa fun olowo. Lọya Latunde Johnson lo wa fun Severino.

## "AKI WA NINU IJỌGBỌN—KA TUN FA KUN AKITIYAN"

Ni ijọ keji lelogun oṣu *September* 1924, ni Ọgbẹni Thomas gba idajọ fun owo rẹ to ya Ọgbẹni Severino yi jẹ ẹnikan ti oju ndun lati ọdun pupọ sẹhin Ni asiko to ya owo yi ni 1918 ni oju ndun Ọgbẹni Severino. Lọya Taylor ni on fẹ ri ninu apoti, nitori on ni ọrọ lati bi, lẹhin igbati Lọya rẹ ni awọn ko le daba bi awọn ti ma san owo yi, owo na to iwọn ẹgbẹta pọun nitori ẹniti ojẹ owo yi ko le san owo nitori ko le ṣiṣẹ nigbati oju rẹ mejeji ndun, Ọgbẹni Severino bọ sinu apoti oni ón gbe Bamgboṣe Street ni Eko. Baba on loni ile ti on gbe nisisiyi o si ti ku ni iye ọdun pupọ ile yi ni Baba on gbe ko to ku pẹlu iya on, ọmọ meji Baba on fi silẹ, on ati aburo on obirin, ile yi ile ti on pẹlu aburo on obirin ni, ni 1918 on ya owo lọwọ Thomas, ologbe Lọya Forsythe lo ṣe iwe fun awọn nigbati on fi ile yi ya wo lọwọ Thomas Ọgbẹni Forsythe ko bi on wipe awọn melo lo ni ile, bo ba bi on ni on ko ba sọ fun Ni ọdun 1923 ni on tun ya owo kun lọwọ Ọgbẹni Thomas ati pe iwọ Lọya Taylor lo ṣe iwe rẹ, otito awọn ọmọ on ṣe ẹleri ninu iwe na ati ẹbi on. njẹ o le mu aṣẹ wa wipe ki wọn pin ile si meji ki Thomas ta ipin tirẹ kuro ninu rẹ. Severino ni agbẹdọ nitori ile ẹbi ni, Taylor bere pe tani awọn ẹbi na. O ni on ati aburo on obirin ati ọmọ awọn mejeji, on si fẹ ki awọn ọmọ on wa ba ile yi. O ni owo ti on gba lọwọ Thoma ni 1918, ni on fi san owo ti on ti ya lọwọ Akodu Elliott ni 1912, ti on pẹlu aburo on obirin jijọ ya nigbana, eyi lo mu Taylor lati bi wipe ki lo ṣe ti iwọ Severino ko sọ fun Lọya Forsythe wipe ẹnyin meji loni ile, o ni ko bi on lere ni ko jẹ ki on sọ fun a ko ma sọ oriṣiriṣi ọrẹ to ṣẹlẹ ninu ẹjọ yi. Taylor ni njẹ bawo lo ṣe fẹ san owo yi. Oni bi oju ba san, Lọya Taylor sọbẹ nigbati o gba owo ni 1918 o ni larin ọdun kan tabi meji on asan, on ni bẹni ṣe on ro wipe oju yi ati san Ni 1923 o tun bẹrẹ kun owo yi o ni bẹni nitori pe on ni ero wipe bi oju yi ba ti san on yio san owo na. A ko mọ nkan ti a ba wi bi ẹniti ori enia ninu ipo bayi to nya lowo ni ojẹbi a ko mọ ẹnu, wa ko gba lati sọ. Lọya Taylor ni ki Adajọ mu Ọgbẹni Severino ninu ofin *Supreme Court Ordinance Ord* 46 nitoripe o gba owo yi nigbati o mọ wipe oju ndun o si kọ wipe on ko fẹ ki wọn ta ipin ti on ninu ile yi. Nitori na eyi to Adajọ lati ro fun wipe ki wọn gbe ọkunrin yi pamọ si ọgba ẹwọn. Ofin na niyi:—

*ORDER 46,*

*Execution of Decrees by Imprisonment.*

2. *Misconduct of Judgment Debtor.*

7. *Sub Sec*

(1) *That the judgment debtor has then or has had since the making of the decree sufficient means to pay the money directed to be paid by him, or part hereof, and refuses or neglects, or has refused or neglected, to pay the same; or*

(3) *The the debt or liability in respect of which the decree has been made, has contracted or incurred by him by frand or false pretence or breach of trust committed by him, or by reason of any damages which he has been adjudged to pay on account of any assult or slander committed by him; or*

*then and in any such case the Court may issue a warrant for the arrest of such judgment debtor and his detention in custody, or for his detention if already in custody, until further order, or if it thinks fit may make an order calling upon such judgment debtor to showed cause why he should not be punished for his misconduct.*

Adajo gba on ti Loya Taylor wi, lẹhin ti Loya Johnson ni ipo on diju gẹgẹ bi iwọ Adajọ ti mọ. lẹhin eyi ni Adajọ paṣẹ wipe ki wọn la gbe Ogbẹni Severino pamọ si ọgba ẹwọn ki Lọya Taylor tun wa gba aṣẹ miran.

A ko rohin ẹjọ yi lati tu aṣiri ẹnikẹni ṣugbọn fun ẹniti ko mọ on to nṣẹlẹ ni ile Ẹjọ ati wipe pataki fun awọn to ma nfi owo lowo da agunla, ati awọn to ma nro wipe ko si loju ki kan saya. Ofin nipa pupọ, ojojumọ ni enia kọ ọgbọn ni ile Ẹjọ. "Nwọn ni olowo ki jorogan, ki iwọfa ma jẹ agun matẹ. *Owe ni o.*

Ni ijọ *Tuesday* ogun jọ oṣu yi ni iwaju Ọlọla Frederick Alan Vander Meulen

*Judgment*—Idajọ

suit No. 435 of 1924.

Joseph Patrick Dawodu

*Versus*

B. Anderson & Coy,

Loya E. O. Moore ati J. T. N. Cole lo wa fun Dawodu. Oyinbo ti orukọ rẹ njẹ Bertic Skjold on ni olotu awọn Oniṣowo yi ko gba Lọya, ohun ti Dawodu pe ẹjọ fun ni yi :—

"*£200. as damages for breach of an Agreement in writing made in Lagos on the 5th day of September, 1924, for the sale and delivery to the plaintiff of 100 bales of round lod.*"

Ni ijo kẹdogun oṣu yi ni wọn ro ẹjọ na, ki Adajọ to wa fi opin si. Ninu idajọ yi, Adajọ wọn ni wọn ko ṣe ipin wipe bi ọja yi ko ba de lasiko bayi tabi wipe asiko bayi ni o ni lati de, *( No definite date fixed on the Contract )* ati wipe Adajọ Adajọ ni ede ti wọn lo ninu adehun *Will* ati *Should* ninu ede Oyinbo *Will* iyẹn ni itumọ kan ṣugbọn *Should* ko ni. *The word Will is perfectly definite and the word Should not definite*" nitorina ai tete de oja yi ki ṣe ẹjọ Oyinbo yi nitori ko si ipinu igbati oni lati de. Ẹnikẹni to ba wa ni kotu yio ri wipe Lọya mejeji yi ṣiṣẹ gidigini ẹnu ko si ni ya ẹnikẹni wipe bi aba gbọ "gbi" awọn loda Oyinbo yi. Ṣugbọn lẹhin ti Adajọ ti fi jigi oju rẹ wo ọrọ na. O ni on da awọn Oyinbo B. Anderson & Coy lare ki Dawodu si san pọun meje ṣile meje owo irin ẹsẹ fun wọn.

Irohin yi fun ẹnyin ti ẹma nṣe iwe Adehun lọdọ Oyinbo kẹ le ṣọra fun ọrọ kekeke miran ti nwọn ma lo fun nyin, ti o si jẹ wipe itunmọ meji lo ma ni, nitori bi ẹma fi ọwọ si iwe, ẹ mu irufẹ iwe bẹ lọ si ọdọ awọn olofin ki wọn yẹ wo fun nyin bi bẹ kọ, ni ijọ miran iwe na adi iwe *Aramu Kandu.*

ATOLUGBOKUN.

---

## FROM THE EDITOR'S OBSERVATORY.

### "One Wanderer returned"

On reading the Editorial Notes in the last issue of our Cotem *The Nigerian Spectator*, we cannot help giving vent to the above remarks : Indeed, strange things do happen : truth is stranger than fiction, *verb sap.*

### Publish it not in Askelon !!!

Dame rumour has it that in the forthcoming meeting of the Legislative Council on or about the 7th *Proximo* the Head of the Executive will likely deliver an address probably of a thundering nature : methinks a wag dins in my ears the well-known Asquithian phrase :—Wait and see.

### Salvation Army, to the Fore !

A successful Revival Campaign meeting was held at the Glover Memorial Hall, in the evening of Wednesday last, when several Artistes, members of the body, entertained the audience to a series of select songs and recitations. It is interesting to see how Lieut-Colonel Souter a sexagenarian in appearance, was frisking about the dais to the amusement of the audience as if he was a youngman of two and thirty In the Tronbone Solo by Capt. da Costa, which was nicely accompanied by Mr. J. Ade Olukunle a bandsman, the Capt. showed his complete mastery of the instrument. Floreat, Ologun Igbala !!!

### Alas my Brother !

We deeply regret to chronicle the death of Mr. Joseph Belo Thomas Supervising Sanitary Inspector, Lagos Town Council, and a Jockey of no mean order, which occurred at his residence 35. Odunfa Street, Anikantamo, Lagos : the deceased was a nephew of the lamented Andrew Wilkinson Thomas's. R.I.P.

---

## SUFFER LITTLE CHILDREN

The Little Flock Society of the African Bethel Church will give a grand native Entertainment at Bethel Church on Friday the 30th inst., at 8 p.m. Chair Mr. N. A. Ṣolade.

---

## A Cause Celebre.

Congratulations to our Muhammadan Brethren The Jamat Muslims at home and abroad, on the successful issue of the Great Cathedral Mosque Case which ended in their victory yester-morning as the Appeal which was lodged by the Alli Balogun party against the Judgment of the Court which was delivered by His Honour Sir F. A. Vander Meulen, the Acting Chief Justice on the 20th March last, was *dismissed* by The full Court yesterday with 40 guineas costs against the Appellants: the total costs of the Court below and the Full Court against the same party being the *trifle sum* of 190 guineas !!!

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)
Masses Isin Arọ.
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)
(Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S ) Lafiaji.)
MORNING. 7—8 8.30—9.30
EVENING. 5.45—6.30

**ANGLICAN**

Time. Preacher
9 a.m. Christ Church. The Vicar
6.30 p.m. do. do
9 a.m. St. Paul's (Breadfruit) Rev. Jas. Pearse
6.30p.m. do. Rev. H. V. E. Johnson
9 a.m. St. John's (Aroloya) do
6.30 p.m. do.
9 a.m. & 6.30 p.m. St. Peter's (Alapako)
Rev. S. V. Latunde
9 a.m. & 6.30 p.m. Holy Trinity (Ebute-Ero)
Rev S. J. Gansallo
9 a.m. St. David's (Jordan) Rev. J. H. Ogunro
6.30 p.m. do. do.

**WESLEYAN**

10.30 a.m. Tinubu Rev. L. R. Potts Johnson
7 p.m. do. Rev. A. N. Cole
10.30 a.m. Ereko Rev. D. A. Bababunmi
7 p.m. do. Bro. J. W. Smith
10.30 a.m. Olowogbowo Rev. E.E. Williams
7 p.m. do. Rev. S. A.Pearce
10.30 a.m. Ọbun Eko do.
7 p.m. do Bro. C. W. Faulkner-Shaw

**AFRICAN (COMMUNION)**

9 a.m. Jehovah Shalom Bro. W. K. Fatuuwa
7 p.m. do. Bro. J. A. Laleyẹ
9 a.m. Christ Church (Ebute Mẹta)
Bro. V. E. Ọlaleyẹ
7 p.m. do. Bro. A. M. Williams
9 a.m. Bethel Bro. A. Aboyade Cole
6.30 p.m. do Rev. I. O. Oyekunle
9 a.m. Zion
6.30 p.m. do
9 a.m. Salem Church (Ebute Mẹta)

6.30 p.m. do.
9 a.m. Bethlehem Church (Ebute Mẹta)
do.
10. a.m. African Methodist Bro. H. A. Williams
do Bro. I. O. Fatolu

**FIRST BAPTIST CHURCH**

10.30 a.m. Rev. J. R. Williams.
6.30 p.m. do.

**(EBENEZER BAPTIST)**

9 a.m. Rev. E. C. Alabi
6.30 p.m. do.
9 a.m. Ararọmi (Baptist)
6 p.m.

**ISOLARIAN BROTHERHOOD.**

7.30 a.m. Ilupesi Resp'ble Sister Eyiyẹmi Pearse
7 p.m. The Founder.

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM.)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde.
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣe
(Central Mosque. Arọloya Street.)

**ZION CONGREGATIONAL**

9 a.m. Kakawa St. Locum Tenens.
7 p.m. do. do.

**SALVATION ARMY**

10 a.m. Glover Memorial Hall
Lt.-Colonel George. H. & Mrs Souter.
7 p.m. do.

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m. Open Air Service at Campbell Square
Wm. C. T. Terrell.

---

ỌMỌ OKUYANMUYANMU

Gbogbo awọn ọmọ Oloye ni Eko afi agbegbe rẹ lo npejọ si Ilupesi Ẹnu-ọwa, ni ọ'jọ Satide Satide lati ma gbero ohun ti yio jasi idagbaṣoke ilu wọn.

Ẹnikeji, o ti fi oruko sile nibọ bọ? Ow kọ ni a fi nwọ ẹgbẹ yi, ọla ni, o ni ipo ninu ẹgbẹ yi, niwọn ti o ba ti jẹ ọkan ninu ọmọ oye wọnyi.

1. Akarigberi
2. Ọgalade
3. Idejọ
4. Ogboni Olorogun

"Ire ilu rẹ ni ki o jẹ ẹdun ero rẹ"

JAMES ỌLADIPỌ HOTON
DAVID AJE OGUNLANA
*Awọn Akọwe Ẹgbẹ.*

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "Excelsior" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI, na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa Pokun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at A. Kessler's Establishment, 7, Labinjo Lane, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

ẸNIKEJI,

Aşọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3, St. John *Street*, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

**GOOD MARKET.**

Gonorrhea Specific, Moloke Mose, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

Cable Address:—
"Steinafrik" HAMBURG

**E. H. STEIN & Co.**

HAMBURG, Neurwall 16/18.
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos:—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

**Ruby Plates! Ruby Plates!! Ruby Plates!!!**

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from:—

DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.

# A. Kessler,

7, Labinjo Lane,

Williams Street,

**P.O. Box 459**

Highly Recommended :




THE

## Pilsener Beer

*"Crystall" Brand*

*Light & Sparkling*

Per Case

**32s.**

**Send for a trial case to-day and convince yourself of the first quality of this Beer.**

## White's Golden Female Tonic

A Splendid Remedy for Female diseases such as :—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhœa (White's), Cramp, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries, A tendency to Miscarriage etc., etc.,

**Made and sold only by** VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B : Not obtainable elsewhere*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN

Egbogi yi dara ṣpupọ fun Aboyun, iju, Eda Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ ati oriṣiriṣi arun miṣ ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

"SHAKE THE BOTTLE."

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi oriṣiriṣi Egbogi lo ṣeṣẹ de fun wa ni tita : awọn bi :—ogun Egbo oriṣiriṣi, ogun Ẹda, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran oriṣiriṣi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.

## Saccharine! Saccharine!! Saccharine!!!

500 Saccharine in packets on sale at H. Campos's Shop, 37, Odunlami Street, Lagos.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ... KOTE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.